# “Àpólà-Orúkọ Agérí” Nínú Èdè Yorùbá

**Ọládélé Awóbùlúyì**
*c/o Department of Linguistics and Languages*
*Adekunle Ajaṣin University*
*Akungba-Akoko, Ondo State*
*Oladele.awobuluyi@gmail.com*

## Àṣamọ̀

*Àbákan fi yé wa pé "ẹ̀yán nìkan" ni gbogbo àwọn wúnrẹ̀n inú "àpólà-orúkọ agérí" inú èdè Yorùbá. Ṣùgbọ́n torí pé ìtúmọ̀ ni àbá náà wò, tí kò wo ìhun pẹ̀lú, kò sí ìkànkan nínú àwọn àpẹẹrẹ márààrún tí ó tọ́ka sí tí ó gbè é. Àwọn ẹ̀rí ajẹmọ́hun èdè náà fi hàn pé àpólà-orúkọ ni gbogbo àwọn ohun tí àbá náà pè ní “ẹ̀yán nìkan.” Dípò “mọ̀ọ́nú orí” tí àbá náà sọ pé ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ tí ó tọka sí, “mọ̀ọ́nú ẹ̀yán oníbààtan” ni ẹ̀rí fi hàn níbẹ̀.*

## Ìfáárà

Àbákan fi yé wa, ní ọ̀pọ̀ ọdún sẹ́yìn, pé àwọn "àpólà-orúkọ agérí" wà nínú èdè Yorùbá. Àlàyé àbá náà tí a rí kà ni pé "tí ẹnìkan bá sọ pé

1. Mo mú mẹ́ta.

ẹni tí ó ń bá sọ̀rọ̀ á ti mọ nǹkan náà. Bóyá **ẹja** ni tàbí **ìwé** ni. Nítorí pé wọ́n mọ orí ọ̀rọ̀ ni wọ́n ṣe lè lo àpólà-orúkọ agérí.

A mọ̀ pé kì í ṣe pé àpólà-orúkọ yìí kò ní orí. Mọ̀ọ́nú (mọ̀-sí-inú) ni orí rẹ̀.

Àpólà-orúkọ agérí ni àpólà-orúkọ tí a lo ẹ̀yán nìkan fún. Bí àpẹẹrẹ, **kékeré kan, ńlá yìí, ti Ayọ̀, dúdú mẹ́ta yẹn** nínú àwọn ìsọ wọ̀nyí:

2. Mo rí kékeré kan.
3. Ńlá yìí dára tó.
4. Mo ti gba ti Ayọ̀.
5. A ti rí dúdú mẹ́ta yẹn.

Ọ̀pọ̀ nǹkan ni ó ń fẹ́ àlàyé síwájú sí i nínú àlàyé òkè yìí. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ǹjẹ́ orí tí a ti gé kúrò lè wà ní àyè rẹ̀ ààrọ̀-ọjọ́ mọ́? Èèyàn ì bá rò pé àpólà-orúkọ tí a ti gé orí rẹ̀ kúrò kò lè ní orí kànkan mọ́, àfi bí àlàyé náà ti tẹ̀ síwájú, tí ó ń fi yé wa pé "Kì í ṣe pé àpólà[-orúkọ tí a ti gé orí rẹ̀ kúrò] yìí kò ní orí [mọ́]. Mọ̀ọ́nú (mọ̀-sí-inú) ni orí rẹ̀." Kí ni àǹfàní tàbí ìwúlò kí á pè é ní agérí, nígbà tí a mọ̀ pé ó ṣì ní orí? Ibo gan-gan ni orí yẹn wà nínú àwọn àpẹẹrẹ (1-5)? Ǹjẹ́ àpólà-orúkọ tilẹ̀ lè wà láìní orí nínú èdè ọmọnìyàn? Kí ni ìtúmọ̀ "ẹ̀yán nìkan" nínú àlàyé yìí? Ṣé ẹ̀yán tí ó ń ṣiṣẹ́ ẹ̀yán ni, àbí èyí tí a fún níṣẹ́ ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ mìíràn ṣe? Ǹjẹ́ ó ṣeé ṣe rárá kí ẹ̀yán wà láìní ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó ń yán nínú èdè ọmọnìyàn?

## Ìwòtúmọ̀-láìwòhun

Ẹ ṣàkíyèsí pé ajẹmọ́hun (a-jẹ-mọ́-ìhun) ni àwọn ìbéèrè wa òkè yìí. Ohun tí ó fà á ni pé ìtúmọ̀ nìkan ni àlàyé náà wò. Kò wo ìhun pẹ̀lú, bí yóò ti hàn nísàlẹ̀ ní abala **3**, níbi tí kò ti jọ

pé ó wo ìṣesí àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ níwájú àwọn wúnrẹ̀n tí ó pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa; ní abala **4**, níbi tí kò ti jọ pé ó ro ti ipò àti iṣẹ́ àwọn wúnrẹ̀n wọ̀nyẹn nínú ìhun gbólóhùn abọ́dé aṣàlàyé; àti ní abala **5**, níbi tí kò ti jọ pé ó fi ìhùwàsí àwọn wúnrẹ̀n náà wé ti àwọn ẹ̀yán gidi nínú ìhun. Ì bá ṣe pé ó wo ìhun àti ìtúmọ̀ papọ̀ ni, bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ (Awobuluyi 2013: 12-16), ì bá ti hàn sí i kedere pé kò sí ìkànkan nínú gbogbo àwọn àpẹẹrẹ tí ó tọ́ka sí wọ̀nyẹn tí ó gbè é rárá.

Iṣẹ́ kankan tí kò bá mọ èyí tẹ́lẹ̀, tí ó sì lọ gbára lé ohun tí àlàyé náà wí, á ṣi ara rẹ̀ lọ́nà, á sì ṣi àwọn èèyàn lọ́nà bá kan náà. Irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ kan ni (Ajiboye 2014: 178). Iṣẹ́ yẹn fi gbogbo ara gbà pé àwọn àpólà-orúkọ kan nínú (1-5) kò ní orí (= agérí ni wọ́n), gẹ́gẹ́ bí àlàyé náà ti wí. Torí pé ó mọ̀ pé dandan ni kí àpólà-orúkọ ní orí nínú abarapá ìpèdè/gbólóhùn ọmọnìyàn, ó ní abirùn ni gbogbo ìpèdè/gbólóhùn bí (1-5) ní láti jẹ́ nínú èdè Yorùbá, nítorí pé wọn kò ní "ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àpólà-orúkọ." Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èrò rẹ̀ yìí ní àrògún, ohun tí ó wí nípa (1-5) kò ṣòótọ́ rárá; ó sì fi ìyẹn ṣi ara rẹ̀ àti àwọn èèyàn lọ́nà pátápátá nípa gbogbo àwọn ìpèdè/gbólóhùn Yorùbá bí (1-5). Ẹ ṣàkíyèsí pé àlàyé gan-gan tí à ń yẹ̀ wò lọ́wọ́ yìí kò sa ìkànkan nínú wọn ní àmì ìràwọ̀; abarapá ìpèdè ni ó ka gbogbo wọn sí. Abarapá ìpèdè ni àwa náà ka gbogbo wọn sí, nítorí pé kò sí òfin kànkan tí àwa mọ̀ tí ìkànkan nínú wọn rú nínú gírámà èdè Yorùbá.

Iṣẹ́ mìíràn bí (Ajiboye 2014: 178) ni àlàyé gan-gan tí à ń yẹ̀ wò níbí yìí. Èrò àti ìgbàgbọ́ rẹ̀, tí ó dìmú ṣinṣin, ni pé kò sí orí kànkan nínú àwọn àpólà-orúkọ kan nínú (1-5). Èrò àti ìgbàgbọ́ yẹn ni ó ṣi (Ajiboye 2014: 178) lọ́nà pátápátá, tí iṣẹ́ yẹn fi pe gbogbo àwọn ìpèdè bí (1-5) ní abirùn. Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀, ohun tí ó tọ̀nà kì í ṣini lọ́nà; ohun tí kò tọ̀nà nìkan ni ó máa ń ṣini lọ́nà. Nítorí náà, ṣíṣì tí èrò àti ìgbàgbọ́ àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí ṣi (Ajiboye 2014: 178) lọ́nà fi hàn gbangba pé èrò àti ìgbàgbọ́ rẹ̀ yẹn kò tọ̀nà. Nǹkan mìíràn tí ó tún fi ìyẹn hàn ni abarapá tí gbogbo àwọn àpẹẹrẹ bí (1-5) yà. (Ara ìdí nìyìí tí a fi sọ ọ́ lókè pé àwọn àpẹẹrẹ inú (1-5) kò gbe àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí rárá.) Bí irú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyẹn kò bá ní orí rárá nínú àwọn àpólà-orúkọ wọn kan ìyẹn, bí ó bá ṣe pé "ẹ̀yán nìkan" ni ó kù sínú wọn ní tòótọ́ – abirùn paraku ni gbogbo wọn ì bá yà! Ṣùgbọ́n wọn kò ya abirùn rárá; kìkì ìdí tí wọn kò sì fi yà á ni pé, ní gàsíkíá, orí gidi (ìyẹn, èyí tí kò fara sin) wà nínú àwọn àpólà-orúkọ gbogbo wọn, bí yóò ti hàn kedere ní abala **3-5** nísàlẹ̀.

Taiwo (2015) náà kò ṣàìní ìpín tirẹ̀ lára àṣìṣe àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí. Lóòótọ́, iṣẹ́ yẹn kò gbà pé àwọn àpólà-orúkọ kan nínú (1-5) kò ní orí, bí (Ajiboye 2014: 178) ti ṣe. Kàkà bẹ́ẹ̀, ó ní wọ́n ní orí. Ó ní orí wọn náà máa ń fara sin ni, tí “ẹ̀yán nìkan” á sì fara hàn níbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí ó gùn lé ti wí. Ṣùgbọ́n ohun gan-gan tí iṣẹ́ yẹn fi eléyìí wí, láìfiyè sí i dáadáa, ni pé ohùn àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ kò níí máa yí padà rárá níwáju gbogbo àwọn àpólà-orúkọ tí ó sọ

pé orí wọn fara sin nínú (1-5). Àmọ́, bí yóò ti hàn kedere ní abala **3** nísàlẹ̀, ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ rárá.

### Ìyípadà Ohùn Ọ̀rọ̀-Ìṣe Olóhùn-Ìsàlẹ̀ Àdámọ́

Ohun gan-gan tí àwa rò pé ó mú kí àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí fúnka mọ́ ìtúmọ̀ nìkan ni "**mọ̀ọ́nú**," ọ̀kan lára àwọn ọ̀rọ̀ tí ó lò nínú àyọlò tí ó wà lókè. Ó jọ pé ìgbàgbọ́ tí ó pilẹ̀ àlàyé náà ni pé, bí wúnrẹ̀n kànkan bá jẹ́ mọ̀ọ́nú, àyè rẹ̀ gbọ́dọ̀ ṣófo ni nínú ìhun, bí ti apá kejì àpẹẹrẹ yìí:

6. Ìwọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀; èmi náà dé– !

Mọ̀ọ́nú ni **adé ìlẹ̀kẹ̀** jẹ́ lóòótọ́ fún olùsọ̀rọ̀ àti ẹni tí ó ń bá sọ̀rọ̀ ní apá kejì àpẹẹrẹ yìí. Àyè rẹ̀ tí ó ṣófo ni a sa àmì "– " sí nínú àpẹẹrẹ náà. Ṣùgbọ́n wúnrẹ̀n lè jẹ́ mọ̀ọ́nú kí àyè rẹ̀ má sì ṣófo! Àpẹẹrẹ ni tiohun gan-gan tí**ẹ́**dúró fún nínú àpẹẹrẹ kéjì yìí.

7. Mo ti jẹ ẹ́.

Ẹni tí ó sọ gbólóhùn yìí àti ẹni tí ó sọ ọ́ sí nìkan ni ó lè mọ ohun gan-gan tí **ẹ́** dúró fún. Ìyẹn ni pé mọ̀ọ́nú ni kinní ọ̀hún jẹ́ fún wọn. Àyè rẹ̀ kò ṣófo nínú àpẹẹrẹ tuntun yìí. Àyè yẹn gan-gan ni **ẹ́** wà níbẹ̀.

Torí pé "mọ̀ọ́nú" pé oríṣi méjì bí a ṣe rí i yìí, a ní láti bèrè irú rẹ̀ gan-gan tí ó wà nínú (1-5). Ṣé èyí tí àyè rẹ̀ máa ń ṣófo nínú ìhun ni, àbí èyí tí àyè rẹ̀ kì í ṣófo? Òfin pàtàkì kan nínú gírámà èdè Yorùbá tí a lè fi dáhùn ìbéèrè yìí lọ́nà tí ó

dájú ṣáká ni èyí tí ó de ohùn àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́. Gẹ́gẹ́ bí àwọn alàgbà Bamgboṣe ti gbé òfin náà kalẹ̀ nínú ìwé wọn (Bamgboṣe 1990: 133), "Nígbà tí ọ̀rọ̀-ìṣe bá gba **ọ̀rọ̀-orúkọ** gẹ́gẹ́ bí àbọ̀, ìyípadà máa ń ṣẹlẹ̀ sí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó bá ní ohùn ìsàlẹ̀. Ohùn yìí gbọ́dọ̀ di ohùn àárín. Bí àpẹẹrẹ:

8.rò: Mo ro ẹ̀fọ́.
9.rà: Mo ra ẹran.
10. tà: Mo ta ìwé."

Kìkì àfikún tí a ní láti ṣe sí ohun tí àwọn alàgbà wí yìí ni pé, bí ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ kò bá gba àbọ̀ rárá, tàbí tí àyè àbọ̀ rẹ̀ bá ṣófo, tàbí tí àbọ̀ yẹn bá fara sin, ohùn rẹ̀ kò níí yí padà rárá. Ẹ̀yin, ẹ wo:

11. Mo rí èsì gbà kíá.

Nínú àpẹẹrẹ yìí, **kíá** kọ́ ni àbọ̀ fún **gbà**. Ìyẹn ni ohùn onítibí yìí kò fi yí padà. **Èsì** ni àbọ̀ **gbà**. Ṣùgbọ́n kò fara hàn lẹ́yìn onítibí yìí. Èyí ni ìdí kéjì tí ohùn **gbà** kò fi yí padà nínú àpẹẹrẹ wa yìí kan náà.

Ìbéèrè tí ó kàn nísìn yìí, lẹ́yìn àlàyé tí a ti ṣe lórí òfin tí ó de ohùn àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́, òun ni, "Ǹjẹ́ ohùn irú àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ máa ń yí padà, àbí kì í yí padà, bí àwọn wúnrẹ̀n tí àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa bá tẹ̀lé wọn?" Bí ohùn wọn kò bá ń yí padà níbẹ̀, a jẹ́ pé "ẹ̀yán nìkan" ni àwọn wúrẹ̀n náà ní tòótọ́; àyè àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó jẹ́ orí fún wọn nínú àpólà-orúkọ sì ṣófo tàbí orí

náà kò fara hàn, gẹ́gẹ́ bí àlàyé náà àti (Taiwo 2015) ti wí. Ẹ̀wẹ̀, bí ohùn ẹ̀yà ọ̀rọ̀-ìṣe tí a wí yìí bá ń yí padà níbẹ̀, a jẹ́ pé àyè àbọ̀ wọn kò ṣófo rárá; àwọn wúnrẹ̀n gan-gan tí àlàyé yẹn pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa ni àbọ̀ wọn; àwọn nǹkan mìíràn tí ó jẹ́ mọ̀ọ́nú ni àwọn àbọ̀ wọ̀nyẹn sì ń dúró fún níbẹ̀, gẹ́gẹ́ bí (Awobuluyi 2013: 35-40) ti wí.

Ẹ jẹ́ kí á fi eléyìí sọ́kàn, kí á fi wo ìkẹ́rin nínú àwọn ìpèdè tí àlàyé náà fi ṣàpẹẹrẹ ìlò àwọn wúnrẹ̀n tí ó pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa. Àpẹẹrẹ náà ni:

4. Mo ti gba *ti* Ayọ̀.

Ǹjẹ́ òhùn **gbà** yí padà níbẹ̀, àbí kò yí padà? Ó kúkú yí padà! (Ìdí mìíràn rè é tí a fi sọ ọ́ lókè pé àwọn àpẹẹrẹ (1-5) kò gbe àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí.) Kí ni yíyípadà ohùn ọ̀rọ̀-ìṣe yẹn fi hàn níbẹ̀? Ohun méjì ni. Ọ̀kan ni pé àyè orí àbọ̀ rẹ̀ kò ṣófo, bẹ́ẹ̀ ni orí àbọ̀ rẹ̀ kò sì fara sin rárá. Ìkéjì ni pé "ẹ̀yán nìkan" kọ́ ni ó tẹ̀lé **gbà** níbẹ̀, gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí ti fẹ́ kí á gbàgbọ́. Ọ̀rọ̀-orúkọ kan, pẹ̀lú ẹ̀yán rẹ̀, ni ó tẹ̀lé e gbọ̀ngbọ̀n-gbọ̀n níbẹ̀; **ọ̀rọ̀-orúkọ** yẹn, **ti**, nìkan sì ni ó lágbára láti mú kí ohùn ọ̀rọ̀-ìṣe yẹn yí padà, gẹ́gẹ́ bí òfin tí a tọ́ka sí lókè ti wí (wo (Awobuluyi 2016b) fún àlàyé kíkún nípa **ti** gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ nínú èdè Yorùbá òde-òní).

Wà yìí o, iwájú **ti Ayọ̀** nìkan kọ́ ni ohùn **gbà** ti máa ń yí padà– èyí, ohun tíkò jọ pé àwọn iṣẹ́ tí ó fara mọ́ àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí fi sí èrò wọn rárá. Iwájú gbogbo àwọn wúnrẹ̀n tí àlàyé náà pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa nínú (1-5) ni ó ti máa ń

yí padà, gẹ́gẹ́ bí òfin tí ó de ohùn àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ ti gbà. Ẹ̀yin, ẹ wo:

12. Mo gba *mẹ́ta*.
13. Mo gba *kékeré* kan.
14. Mo ti gba *ńlá* yìí.
15. Mo ti gba *dúdú* mẹ́ta wọ̀nyẹn/yẹn.

Yàtọ̀ sí pé a lo **ńlá yìí** ní ipò àbọ̀ nínú (14) dípò ti olùwà tí ó wà nínú (3), bí àlàyé náà ṣe lo gbogbo àwọn wúnrẹ̀n tí ó pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa lókè nínú (1-5), bẹ́ẹ̀ ni àwa náà ṣe lò wọ́n níbí yìí. Ẹ̀kọ́ tí yíyípadà ohùn **gbà** kọ́ wa nípa (4), òun náà ni ó kọ́ wa nípa (12-15). Ẹ̀kọ́ náà sì ni péàpólà-orúkọ – ìyẹn, ọ̀rọ̀-orúkọ pọ́ńbélé tàbí ọ̀rọ̀-orúkọ pẹ̀lú (àwọn) ẹ̀yán rẹ̀– ni ó tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe yẹn gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ rẹ̀ níbẹ̀.

## Olùwà àti Àbọ̀ nínú Àwọn Gbólóhùn Abọ́dé Aṣàlàyé

Gẹ́gẹ́ bí a ti wí lókè, ìtúmọ̀ nìkan ni àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí wò, tí ó fi pe àwọn wúnrẹ̀n tí à ń sọ̀rọ̀ wọn wọ̀nyí ní "ẹ̀yán nìkan" nínú àwọn àpẹẹrẹ tí ó tọ́ka sí fún wa. Àwọn àpẹẹrẹ náà ni a dà kọ sí ìsàlẹ̀ yìí fún ìrọ̀rùn ẹ̀yin òǹkàwé.

1. Mo mú mẹ́ta.
2. Mo rí kékeré kan.
3. Ńlá yìí dára tó.
4. Mo ti gba ti Ayọ̀.
5. A ti rí dúdú mẹ́ta yẹn.

Ìtúmọ̀ nìkan tí àlàyé náà wò ni kò ṣe kíyèsí yíyí tí ohùn **gbà** yípadà nínú (4), àti ohun tí yíyípadà ohùn rẹ̀ kọ́ wa– ìyẹn, (i) pé kò sí àyè kànkan tí ó ṣófo tàbí tí ọ̀rọ̀ tí ó wà níbẹ̀ fara sin níwájú **tiAyọ̀**, àti (ii) pé nítorí náà, ipa àpólà-orúkọ aṣàbọ̀ (a-ṣe-àbọ̀) ni **ti Ayọ̀** kó níbẹ̀.

Ó yẹ kí àlàyé tí a wí yìí ti wo ìhun gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yòókù lókè yìí náà. Ṣùgbọ́n kìkì ohun tí ó jọ bẹ́ẹ̀ tí ó ṣe ni pé, ó ka gbogbo wọn sí gbólóhun abarapá, gẹ́gẹ́ bí àwa náà ti ṣe. Ẹ ṣàkíyèsí pé kò sa ìkànkan nínú wọn ní àmì ìràwọ̀, gẹ́gẹ́ bí a ti wí lókè. Ohun méjì ni abarapá tí àwọn àpẹẹrẹ náà yà fi hàn. A ti tọ́ka sí ọ̀kan nínú wọn lókè– ìyẹn, pé kò sí àyè kànkan tí ó ṣófo níwájú àbọ̀ ìkànkan wọn. Èkéjì ni pé gbogbo fọ́nrán-ìhun tí ó yẹ kí ó wà nínú ìkọ̀ọ̀kan wọn ni ó wà níbẹ̀. Gbólóhùn abọ́dé aṣàlàyé sì ni ìkọ̀ọ̀kan wọn. Nítorí náà, ó kéré tán, olùwà àti àpólà-ìṣe gbọ́dọ̀ wà gẹ́gẹ́ bí fọ́nrán-ìhun nínú ìkọ̀ọ̀kan wọn. (Ìdí mìíràn nìyìí tí a fi sọ pé àwọn àpẹẹrẹ inú (1-5) kò gbe àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí rárá.)

Nínú gbogbo èdè ọmọnìyàn, gẹ́gẹ́ bí àwọn onímọ̀ gírámà ti mọ̀ dájú, ọ̀rọ̀-orúkọ, àsọdorúkọ, àti àwọn ẹ̀yà ọ̀rọ̀ mìíràn tí a fún ní iṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ ṣe nìkan ni ó máa ń kó ipa olùwà nínú gbólóhùn. Iṣẹ́kíṣẹ́ tí ó bá mọ eléyìí gbọ́dọ̀ pe **ńlá yìí** nínú (3) ní àpólà-orúkọ, nínú èyí tí **ńlá** ti jẹ́ ẹ̀yán tí a fún ní iṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ ṣe, tí**yìí** sì jẹ́ ẹ̀yán tí ó ń yán an.

Ìtúmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó wà nínú (1-2, 4-5) fi hàn pé ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ (a-gba-àbọ̀) ni gbogbo wọn. Ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ sì gbọ́dọ̀ ní àbọ̀ tí ó ń bá a ṣiṣẹ́ nínú àpólà-ìṣe. Nínú èdè

Yorùbá, ń ṣe ni àbọ̀ máa ń tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń bá ṣiṣẹ́ gbọ̀ngbọ̀n-gbọ̀n. **Mẹ́ta, kèkeré kan, ti Ayọ̀,** àti **dúdúmẹ́ta yẹn** ni àwọn fọ́nrán-ìhun tí ó tẹ̀lé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe inú (1-2, 4-5) gbọ̀ngbọ̀n-gbọ̀n. Nítorí náà, àwọn ni àbọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyẹn gbọ́dọ̀ jẹ́. Ọ̀rọ̀-orúkọ, àsọdorúkọ, tàbí ẹ̀yà ọ̀rọ̀ mìíràn tí a fún ní iṣẹ́ ọ̀rọ̀-orúkọ ṣe nìkan ni ó ń kó ipa àbọ̀ nínú gbogbo èdè ọmọnìyàn, tí ó fi kan èdè Yorùbá. Nítorí ìdí èyí, ọ̀rọ̀-orúkọ ni **mẹ́ta, kékeré, ti,** àti **dúdú** gbọ́dọ̀ jẹ́ nínú (1-2, 4-5), kí **kan**jẹ́ ẹ̀yán fún **kékeré** nínú (2), kí**Ayọ̀**jẹ́ ẹ̀yán fún **ti** nínú (4), kí**mẹ́ta yẹn**sì jẹ́ ẹ̀yán fún **dúdú** nínú (5).

## Ẹ̀rí Inú Àsọtẹ́lẹ̀

Bí a bá fi wúnrẹ̀n kan sí ìsọ̀rí kan yálà nínú gbólóhùn tàbí nínú gírámà, àsọtẹ́lẹ̀ tí a fi ìyẹn sọ nípa rẹ̀ ni pé yóò máa hùwà níbẹ̀ ni, bí àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù nínú ìsọ̀rí kan náà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí a bá pe ọ̀rọ̀ kan ní ọ̀rọ̀-orúkọ, ohun gan-gan tí a fi ìyẹn wí nípa rẹ̀ ni pé yóò máa hùwà nínú ìhun ni, bí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù ti ń ṣe níbẹ̀. Bí ó bá ṣe ọ̀rọ̀-orúkọ ni ọ̀rọ̀ náà ní tòótọ́, á máa hùwà bí ti àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ yòókù nínú ìhun ni. Ṣùgbọ́n bí kì í bá ń ṣe ọ̀rọ̀-orúkọ ni, kò níí hùwà rárá bí ti àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ gidi nínú ìhun.

Bí a bá fi ojú àlàyé yìí wo ohun tí àlàyé tí a ti ń yẹ̀ wò bọ̀ láti òkè wí, a óò rí i pé ọ̀pọ̀ àsọtẹ́lẹ̀ tí kò ṣẹ ni ó sọ nípa àwọn wúnrẹ̀n tí ó pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa nínú (1-5). Ọ̀kan lára irú àwọn àsọtẹ́lẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn wúnrẹ̀n náà kò níí máa mú kí ohùn àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ yí padà nínú gbólóhùn, nítorí pé "ẹ̀yán nìkan" kì í mú kí ohùn

ọ̀rọ̀-ìṣe yí padà. Ṣùgbọ́n, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú (4, 12-15), ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Àwọn wúnrẹ̀n tí àlàyé náà pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa mú kí ohùn ọ̀rọ̀-ìṣe yí padà nínú gbogbo àpẹẹrẹ wọ̀nyẹn. Ìyẹn sì fi hàn pé wọn kì í ṣe "ẹ̀yán nìkan;" ọ̀rọ̀-orúkọ ni wọ́n, nítorí pé ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan ni ó lágbára láti mú kí ohùn ọ̀rọ̀-ìṣe olóhùn-ìsàlẹ̀ àdámọ́ yí padà. Àsọtẹ́lẹ̀ mìíràn tí àlàyé náà sọ ni pé ẹ̀yán kànkan kò níí lè yán àwọn wúnrẹ̀n náà, nítorí pé ẹ̀yán kì í yán ẹ̀yán nínú èdè Yorùbá—ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan ni wọ́n máa ń yán. Àsọtẹ́lẹ̀ yìí náà kò ṣẹ. Inú (1) nìkan ni kò ti sí ẹ̀yán; ó wà nínú gbogbo àwọn yòókù, ìyẹn, (2-5). Ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan ni àwọn ẹ̀yán lè máa yán nínú (2-5), nítorí pé ọ̀rọ̀-orúkọ nìkan ni àwọn ẹ̀yán máa ń bá ṣiṣẹ́. Eléyìí náà tún fi hàn pé àwọn wúnrẹ̀n tí àlàyé tí à ń yẹ̀ wò yìí pè ní "ẹ̀yán nìkan" fún wa kì í ṣe "ẹ̀yán nìkan" rárá. Ọ̀rọ̀-orúkọ ni wọ́n gbọ́dọ̀ jẹ́, nítorí pé ẹ̀yán ń yán wọn nínú àwọn àpẹẹrẹ mẹ́rin wọ̀nyẹn. Àsọtẹ́lẹ̀ mìíràn tún ni pé kò níí ṣeé ṣe láti gbé àwọn wúnrẹ̀n wọ̀nyẹn wá síwájú (= ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn) fún ìtẹnumọ́, nítorí pé àwọn "ẹ̀yán nìkan" kì í ṣeé gbé wá síwájú bọ̀rọ̀ fún ìtẹnumọ́. Àsọtẹ́lẹ̀ kẹ́ta yìí náà kò ṣẹ, gẹ́gẹ́ bí àwọn àpẹẹrẹ wa wọ̀nyí ti fi hàn:

16. Mẹ́ta ni mo mú.
17. Kékeré kan ni mo rí.
18. Ńlá yìí ni ó dára tó.
19. Ti Ayọ̀ ni mo ti gbà.
20. Dúdú mẹ́ta wọ̀nyẹn/yẹn ni a ti rí.

Kí á má wulẹ̀ fa ọ̀rọ̀ gùn, kò sí àsọtẹ́lẹ̀ mìíràn kànkan tí èèyànlè sọ nípa àwọn wúnrẹ̀n tí à ń sọ̀rọ̀ wọn wọ̀nyí, gẹ́gẹ́ bí "ẹ̀yán nìkan" ní àyè tí wọ́n wà nínú (1-5), tí yóò ṣẹ. Ẹ̀wẹ̀, torí pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni ó máa ń ṣíwájú nígbà gbogbo nínú àpólà-orúkọ èdè Yorùbá, bí a bá ka èyí tí ó ṣíwájú nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn níbẹ̀ sí ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí wúnrẹ̀n tí a lò gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-orúkọ, kò sí àsọtẹ́lẹ̀ tí ó tọ́ tí èèyàn bá sọ nípa wọn, ní àyè yẹn kan náà, tí kò níí ṣẹ. Ẹ̀rí ohun tí a wí yìí ni àwọn àpẹẹrẹ ìlò **ti** gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ tí (Awobuluyi 2013: 20-24, 35) tọ́ka sí, tí ó fi hàn pé ó ń gba fáwẹ̀lì aláfibọ̀, ó ń gba ẹ̀yán, ó ń ṣe amúpé fún atọ́kùn, bẹ́ẹ̀ ni ó sì máa ń ṣiṣẹ́ olùwà àti ti àbọ̀ bí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ti máa ń ṣe. Ẹ̀rí rẹ̀ náà tún ni àwọn àpẹẹrẹ ìlò **méjì, mẹ́ta,** abbl. àti ti **ńlá, dúdú, funfun**, abbl. gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-orúkọ/arọ́pò-orúkọ, tí (Awobuluyi 2013: 37-40) tọ́ka sí, tí ó fi hàn pé wọ́n lè ṣiṣẹ́ olùwà àti ti àbọ̀, wọ́n lè gba ẹ̀yán, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì lè mú kí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ mìíràn tí ó bá wọn rìn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yán oníbààtan gba fáwẹ̀lì aláfibọ̀ bí ó bá ṣe kọ́nsónáǹtì ni ó bẹ̀rẹ̀ wọn, bí àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ mìíràn bẹ́ẹ̀ ti máa ń ṣe. Gbogbo eléyìí fi hàn pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni wọ́n; wọn kì í ṣe "ẹ̀yán nìkan" tí àlàyé tí a ti ń yẹ̀ wò bọ̀ láti òkè pè wọ́n.

## Àyè "Mọ̀ọ́nú Orí" Nínú (1-5)

Àwọn àkíyèsí tí a ti ṣe lókè ní abala **3-5** fi hàn gbangba lápapọ̀ pé àpólà-orúkọ ni gbogbo àwọn wúnrẹ̀n tí àlàyé tí a ti ń yẹ̀ wò bọ̀ pè ní "ẹ̀yán nìkan" nínú (1-5). Ìkọ̀ọ̀kan nínú àpólà-orúkọ wọ̀nyẹn ni ó ní ọ̀rọ̀-orúkọ tí kò fara sin, tí ó sì ń

kó ipa orí nínú wọn. Nígbà tí ọ̀rọ̀ sì ti rí bá yìí, ó di dandan kí á tún bèrè, bí a ti ṣe ní abala **1** lókè, pé ibo gan-gan ni "mọ̀ọ́nú orí" wà nínú (1-5)?

Ìdáhùn ìbéèrè yìí gba ìmọ̀àwọn òfin afọ̀ (*discourse*) tí ó de àwọn àpẹẹrẹ inú (1-5), nítorí pé àwílé àkíyèsí inú afọ̀ (= ìpèdè tí a sọ lẹ́yìn ìpèdè mìíràn nínú afọ̀ kan náà) ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. Àwọn òfin náà ni pé: bí a bá ti dárúkọ kinní kan tẹ́lẹ̀ nínú afọ̀ kan, a kì í sábà á dárúkọ rẹ̀ mọ́ nínú afọ̀ yẹn kan náà. Bí a bá ní láti dárúkọ rẹ̀ níbẹ̀ ní ẹ̀ẹ̀kéjì, ẹ̀ẹ̀kẹ́ta, abbl., a gbọ́dọ̀ fi **náà** sí ẹ̀yìn irú orúkọ bẹ́ẹ̀, bí ti **iṣu** ní ìsàlẹ̀ yìí, láti fi hàn gbangba pé nǹkan kan náà ni a ṣì ń sọ̀rọ̀ lé lórí:

21. Mo bá *iṣu* kan níbẹ̀; mo sì mú *iṣu náà*.

Bí a kò bá fẹ́ẹ́ dárúkọ nǹkan náà mọ́ rárá nítorí pé a ti dárúkọ rẹ̀ tẹ́lẹ̀, ọ̀kan nínú ohun méjì ni a lè ṣe. Yálà kí á fo orúkọ nǹkan náà pátápátá, bí ó bá ṣeé ṣe, bí ti apá kejì inú (6):

6. Ìwọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀; èmi náà dé – !

tàbí kí á fi arọ́pò-orúkọ kan tí ó tọ́ sí i rọ́pò rẹ̀, bí ti (22):

22. Mo bá *iṣu* kan níbẹ̀; mo sì mú *un*.

Ìdáhùn mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a rí tọ́ka sí fún ìbéèrè wa lókè, pé ibo gan-gan ni àyè "mọ̀ọ́nú orí" wà nínú àwọn ìpèdè/gbólóhùn bí (1-5)? Ajiboye (2014) àti àlàyé tí a ti ń

yẹ̀ wò bọ̀ gbàgbọ́ pé iwájú àwọn "ẹ̀yán nìkan" ni àyè "mọ̀ọ́nú orí" wà. Ṣùgbọ́n bí a ti fi hàn ní abala **3** lókè, ibẹ̀ kọ́–kò sí àyè kànkan tí ó ṣófo tí ó lè jẹ́ tirẹ̀ níbẹ̀.

Taiwo (2015) náà gbàgbọ́ pé iwájú àwọn "ẹ̀yán nìkan" ni àyè yẹn wà. Ó ní "mọ̀ọ́nú orí" tí ó wà níbẹ̀ dígbà máa ń fara hàn, bí ti inú (23) nísàlẹ̀ yìí:

23. Mo mú méjì. → Mo mú *ẹyọ* méjì.

Ṣùgbọ́n ìbéèrè tí àpẹẹrẹ yìí yóò mú wáyé lójú-ẹsẹ̀ ni: *ẹyọ méjì kí ni*? Ìtúmọ̀ ìbéèrè yẹn si ni pé,"mọ̀ọ́nú orí" kò pàpà tíì fara hàn!

Lójú (Awobuluyi 2013: 38), àdàmọ̀dì arọ́pò-orúkọ ni ó máa ń wà ní àyè "mọ̀ọ́nú orí" nínú (1-5). Nítorí náà, àdàmọ̀dì arọ́pò-orúkọ ni ó ka **méjì** sí nínú (24),

24. Mo bá ọ̀pọ̀ iṣu níbẹ̀; mo mú *méjì* (nínú wọn).

àpẹẹrẹ tí ó fi ṣàtúnṣe (25).

25. Mo bá ọ̀pọ̀ iṣu níbẹ̀; *mo mú iṣu méjì.[1]

[1]Àwọn kan rò pé ohun tí (Awobuluyi 2013: 38) fi àmì ìràwọ̀ wí níbí yìí ni pé abirùn ìpèdè ni "*Mo mú iṣu méjì." níbi gbogbo nínú èdè Yorùbá òde-òní. Ṣùgbọ́n bẹ́ẹ̀ kọ́! Kìkì ohun tí ó fi wí ni pé abirùn ni ìpèdè náà *ní sàkání èyi tí ó ṣáájú rẹ̀ nínú (25).*(Bóyá àmì ìbéèrè ni ì bá ti sàn láti fi sí ìbẹ̀rẹ̀ ìpèdè náà bá yìí– ?mo mú iṣu méjì– dípò àmì ìràwọ̀.) Ẹ ṣàkíyèsí pé ó rú òfin afọ̀ tí a tọ́ka sí lókè, pé bí a bá ti dárúkọ kinní kan tẹ́lẹ̀ nínú afọ̀ kan, a kì í dárúkọ rẹ̀ (pọ́ńbélé) mọ́níbẹ̀, bí wọ́n ti ṣe nínú (25). Torí ìdí èyi, kò sí ìṣewẹ́kú ajẹmọ́tumọ̀-jẹmọ́hun (*semantico-structural cohesion*) kànkan láàárín ìpèdè yẹn àti èyí tí ó ṣáájú rẹ̀ nínú (25). Ìyẹn ni pé, kò sí nǹkan kan tí ó fi hàn dájú pé àwọn iṣu kan náà tí ọ̀rọ̀ kàn nínú ìpèdè kìíní ni ó kàn nínú ìpèdè kéjì náà.

Ṣùgbọ́n yàtọ̀ sí pé, bí ó ti hàn nínú abala **3-5** lókè, ọ̀rọ̀-orúkọ ni ó sàn kí á kúkú pe **mẹ́ta, ńlá, kékeré, dúdú**, abbl. nínú (1-5),[2] ìfi-fọ́nrán-ìhun-ṣòfò ni ó já sí kí **méjì** àti **wọ́n** jẹ́ arọ́pò-orúkọ tí ó dúró fún nǹkan kan náà, (ìyẹn, **iṣu**), nínú (24) lókè!

Èdè Yorùbá tìkára rẹ̀ ṣe ọ̀nà àbáyọ fún wa nínú ìṣòro òkè yìí. Gẹ́gẹ́ bí a ti wí tẹ́lẹ̀, bí ẹnìkan bá wí pé

1. Mo mú mẹ́ta.

ìbéèrè tí a óò bi onítọ̀hún ni:

26. Mẹ́ta *kí* ni?

Ohun tí ìbéèrè yìí sì ń fẹ́ ni nǹkan gan-gan tí ó jẹ́ mọ̀ọ́nú. Ọ̀rọ̀-orúkọ, (ìyẹn, **iṣu,** torí pé ọ̀rọ̀ **iṣu** ni a ti ń sọ bọ̀), ni kinní ọ̀hún sì gbọ́dọ̀ jẹ́. Wà yìí o, wọ̀fún àyè kan ṣoṣo ni ó ṣófonínú (1).Ẹ̀yìn **mẹ́ta** niàyè náà wà; ti ẹ̀yán sì ni. Bí a bá fi ọ̀rọ̀-orúkọ sí àyè ẹ̀yán, ẹ̀yán oníbàátan ni ó máa ń dà níbẹ̀. Ìdí nìyẹn tí ó fi jẹ́ pé, bí a bá máa sọ (1) ní kíkún, yálà kí ó di (27) bí a bá dárúkọ **iṣu** ní ẹlẹ́ẹ̀kejì nínú afọ̀ kan náà,

27(a). Mo mú mẹ́ta *iṣu náà*.
(b). Mo mú mẹ́ta nínú *iṣu náà*.

[2]Àmọ́, arọ́pò-orúkọ ni ó sàn kí á ka **ti** sí. Gẹ́gẹ́ bí a ti wí nínú (Awobuluyi 2016b), orí fún ẹ̀yán oníbàátan nìkan ni ó máa ń rọ́pò nígbà gbogbo nínú afọ̀ àti nínú ẹ̀yán alálàjẹ́. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, orí ni **ti** (= ohun ìní) jẹ́ fún **Ayọ̀**, ẹ̀yán oníbàátan, nínú (4 = 29(d)). Nǹkan kan tí a ti dárúkọ rẹ̀ sẹ́yìn nínú afọ̀ ni ó dúró fún níbẹ̀.

tàbí kí ó di (28) bí a kò bá dárúkọ rẹ̀ mọ́, tí a sì fi arọ́pò-orúkọ tí ó tọ́ sí i rọ́pò rẹ̀ nínú afọ̀ kan náà, bí àwọn òfin afọ̀ tí a tọ́ka sí lókè ti gbà.

28(a). Mo mú mẹ́ta *wọn*.
(b). Mo mú mẹ́ta nínú *wọn*. (Ẹ rántí pé 'nínú *wọn*' = ní inú *wọn.*)

Àwọn ẹ̀dà bí (28) fún àwọn àpẹẹrẹ yòókù nínú (1-5) nìwọ̀nyí:

29(a). Mo rí kékeré *wọn* kan./Mo rí kékeré kan nínú *wọn*.
(b). Ǹlá *wọn* yìí dára tó./Ǹlá yìí dára tó nínú *wọn*.
(d). Mo ti gba ti Ayọ̀. (Wo ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀ 2 nísàlẹ̀.)
(e). A ti rí dúdú *wọn* mẹ́ta wọ̀nyẹn/yẹn./A ti rí dúdú mẹ́ta wọ̀nyẹn/yẹn nínú *wọn*.

Fún àníkún ìmọ̀ àti òye nípa irú àwọn ìpèdè bá wọ̀nyí, ẹ ṣàkíyèsí pé kò ṣeé ṣe láti fi arọ́pò-orúkọ ẹni kẹ́ta ẹyọ sí àyè tí a fi sílẹ̀ lófo nínú (6),

6. Ìwọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀; èmi náà dé– !

kí ó wáá di (30).

30. Ìwọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀; ?èmi náà dé *e*!

Ìpèdè ti apá kéjì (30)níbí yìí kò mú ọgbọ́n kànkan dání. Ìtúmọ̀ rẹ̀ ni pé àwọn ẹni méjì tí ọ̀rọ̀ kàn jọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀ kan náà ni; bẹ́ẹ̀ orí kan ṣoṣo ni adé kan lè dé lẹ́ẹ̀kan! Kìkì ohun tí a lè wí dípò (30) ni:

31. Ìwọ dé adé ìlẹ̀kẹ̀; èmi náà dé irú *rẹ̀*/ọ̀kan*rẹ̀*!

Ìyẹn ni pé ète tí ó la ìlò "mọ̀ọ́nú ẹ̀yán oníbààtan" lọ nìkan ni a lè lò, bí a bá fẹ́ẹ̀ dí àyè tí ó ṣófo ní apá kéjì (6).

A rò pé gbogbo eléyìí fi hàn kedere pé àyè "mọ̀ọ́nú orí" kọ́ ni ó máa ń ṣófo nínú àwọn ìpèdè bí (1-5), bí àlàyé tí a ti ń yẹ̀ wò bọ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ yìí ti fẹ́ kí á gbàgbọ́. Kàkà bẹ́ẹ̀, ó jọ pé àyè ẹ̀yán oníbààtan ni. Nítorí ìdí èyí, ójọpé ohun tí ó yẹ kí (Awobuluyi 2013: 37-40) ti wí kọ́ ni pé àwọn ọ̀rọ̀ kan tí wọ́n jẹ́ ẹ̀yán aṣòǹkà/ajúwe tẹ́lẹ̀ á di àdàmọ̀dì arọ́pò-orúkọ nínú àwọn ìpèdè bí (1-5). Dípò ìyẹn, ó jọ pé ohun gan-gan tí ó yẹ kí ó ti wí ni pé, nínú àwọn ìpèdè tí a sọ di àwọn àpẹẹrẹ bí (1-5) nínú afọ̀, ẹ̀yán aṣòǹkà/ajúwe tí ó ṣáájú nínú àpólà-orúkọ yóò di ọ̀rọ̀-orúkọ ní àyè orí àpólà-orúkọ tí ó wà yẹn. (Dandan ni o, kí ọ̀rọ̀-orúkọ jẹ́ orí nínú abarapá àpólà-orúkọ!) Orí tí ó ti wà nínú àpólà-orúkọ yẹn kan náà tẹ́lẹ̀, yálà kí ó pòórá pátápátá nítorí pé kò sí àyè orí fún un mọ́ níbẹ̀, tàbí kí ó di ẹ̀yán oníbààtan sí ibẹ̀.[3] Ìyẹn ni pé, bí ó bá di inú afọ̀ tí a ti dárúkọ àwọn **iṣu** kan sẹ́yìn,

---

[3]Níbi tí a rí ọ̀rọ̀ àwọn ẹ̀yà ẹ̀yán yòókù dé lónìí, ó jọ pé orí ẹ̀yán aṣàfihàn àti ti ẹ̀yán aláwẹ́-gbólóhùnmáa ń pòórá pátá pátá ni, láìsí wúnrẹ̀n aṣojú wọn kànkan nínú àpólà-orúkọ tí wọ́n ti pòórá. Àpẹẹrẹ ni:

(a) Ìwé yìí ni mo rà. → Èyí ni mo rà. (ìwé → ø)
(b) Ìwé tí mo rà. → Èyí tí mo rà. (ìwé → ø)

Ó jọ pé ohun tí '**èyí**' ní apá kejì (b) fi hàn ni pé ìpèdè bí 'Ìwé *èyí tí/kì* mo rà' gan-gan ni ó wà ní ìpìlẹ̀ apá kìíní àpẹẹrẹ yẹn nínú gbogbo àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá. Ìyẹn ni àwọn ẹ̀ka-èdè ìlà-oòrùn-mọ́-gúsù fi máa ń wí pé 'Ìwé *yìí* mo (r)à;' tí àwọn ẹ̀ka-èdè ìwọ̀-oòrùn yóò wí pé 'Ìwé *tí* mo rà;' tí àwọn ẹ̀ka-èdè

32. Ó jí ịṣu mẹ́ta kó.

yóò di

33. Ó jí mẹ́ta kó./Ó jí mẹ́ta *wọn* kó./Ó jí mẹ́ta kó nínú *wọn*.
(ịṣu → ø/wọn)

níbi tí **wọn**, arọ́pò-orúkọ ẹ̀yán oníbààtan, ti dúró fún **iṣu**, tí ó jẹ́ orí fún **mẹ́ta** tẹ́lẹ̀.

## Ìkádìí

Gbogbo àwọn àkíyèsí tí a ti ṣe àti àwọn ohun tí a ti wí nínú iṣẹ́ wa yìí jọ bí pé wọ́nfi hàn gbangba-gbàǹgbà pé kò sí "àpólà-orúkọ agérí" kànkan nínú gbogbo àwọn ìpèdè/gbólóhùn Yorùbá bí (1-5). Kàkà bẹ́ẹ̀, àpólà-orúkọ gidi, tí orí rẹ̀kò fara sin rárá, ni ó jọ pé àwọn kan pè ní "àpólà-orúkọ agérí" níbẹ̀. Dípò "mọ̀ọ́nú orí" tí àwọn kannáà rò pé ó wà nínú irú àwọn àpólà-orúkọ bá wọ̀nyẹn, "mọ̀ọ́nú ẹ̀yán oníbààtan" ni ó máa ń wà níbẹ̀. Ṣùgbọ́n gbogbo eléyìí

---

àárín-gbùngbùn yóò sì sọ nǹkan bí 'Ìwé *kì*mọ̀ ọ́rà.' Bí àwọn èèyàn bá sì rántí ohun tí (Awobuluyi 2016a) wí nípa èdè Yorùbá àti èdè Àfá-Òkèàgbè, kò níí yà wọ́n lẹ́nu láti gbọ́ pé oríṣi ìpèdè ìpìlẹ̀ kan náà ni èdè Àfá-Òkèàgbè ń Ìwé *iní í* mu dà = ìwé *èyí tí* mo rà.

**Òun** ni wúnrẹ̀n aṣojú fún orí ẹ̀yán ayẹbírọ̀-sọ́tọ̀ (= abìtẹnumọ́/alátẹnumọ́):

(d) Iṣu ni mo jẹ; òun ni ìwọ náà jẹ. (iṣu → òun)

Gẹ́gẹ́ bí a ti wí ní ìtọsẹ̀-ọ̀rọ̀ 2, '**ti**' ni wúnrẹ̀n aṣojú fún orí ẹ̀yán oníbààtan: ìwé Ayọ̀ → *ti* Ayọ̀ (ìwé → ti)

kò já sí pé kò sí ẹ̀yà àpólà-orúkọ kànkan nínú èdè Yorùbá tí ó fara jọ "àpólà-orúkọ́ agérí!" Irú àpólà-orúkọ bẹ́ẹ̀ wà, tí àwa yóò pè ní "àpólà-orúkọ aforísin/aforímù" (a-fi-orí-mù). Àmọ́ àpẹẹrẹ wọn gan-gan kọ́ ni àlàyé tí a yẹ̀ wò lókè tọ́ka sí. Irú àwọn àpẹẹrẹ tí àwa rò pé ó fi wọ́n hàn kedere ni àwọn tí a sọ̀rọ̀ lé lórí nínú (Awobuluyi 2013: 311-313) àti (Awobuluyi 2015: 23-26).[4] Àwọn ẹ̀rí ajẹmọ́hun wà dáadáa, tí ó fi hàn pé àwọn ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó jẹ́ orí nínú irú àwọn àpẹẹrẹ bá wọ̀nyẹn fara sin ni ní tòótọ́. Ẹ̀yí sì mú kí wọ́n yàtọ̀ gédégédé sí irú àwọn àpẹẹrẹ tí a yẹ̀ wò lókè nínú iṣẹ́ wa yìí.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Ajiboye, Ọladiipọ (2014). 'Wúnrẹ̀n *ti* Inú Àpólà Orúkọ Oníbààtan Kì í Ṣe Ọ̀rọ̀-Orúkọ,' *Yorùbá: Journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria*7.3: 168-184.

Awobuluyi, Ọladele (2013). *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Oṣogbo: Atman Limited.

Awobuluyi, Ọladele (2015). 'Àwọn Atọ́ka Amúpé Inú Èdè Yorùbá,' *Yorùbá: Journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria* 8.1: 18-30.

Awobuluyi, Ọladele (2016a). 'Àwọn Ẹ̀kọ́ tí Èdè Yorùbá àti Èdè Àfá-Òkèàgbè Kọ́ Wa nípa Ara Wọn,' *Yorùbá: Journal of the Yoruba Studies Association of Nigeria* 9.


[4]Ó dunni púpọ̀ púpọ̀ pé orişirísị àṣìtẹ̀ tí kò sí nínú bébà yìí tẹ́lẹ̀ ni ó ti rá wọ̀ ọ́ nígbà tí wọ́n fi máa bá wa tẹ̀ ẹ́ jáde nínú *Yorùbá* 2015.

Awobuluyi, Ọladele (2016b). 'On the Syntax and Semantics of the Noun *Ti* in Yoruba,' nínú ìwé àfiṣàyẹ́sí Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlasope Oyelaran.

Bamgboṣe, Ayọ (1990). *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ibadan: University Press Limited.

Taiwo, Oye (2015). 'Àdàmọ̀dì Ọ̀rọ̀-(Arọ́pò) Orúkọ tàbí Ẹ̀yán?' tí ó kà níbi Àpérò Ẹgbẹ́ ti ọdún 2015 ní Àkùngbá-Àkókó.